Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Elti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fiwe yi se ikede si awon Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa, o pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranse si enibe mo.

VOL. XI No. 616. LAGOS, SATURDAY, MARCH 21 — MARCH 27, 1959. KOBO MEJI (2d)

# Iwadi Oro Lori Awon Oloja, Abioye Dosunmu Pe Oku Orun Jeri

EKO. Awon eleri ti Ogbeni Beyioku ti pe lati wa jeri gegebi awon Lagos Town Council ti se gba owo lowo won bere si poora, nwon bere si wa won kiri. Ogbeni Beyioku so fun oyinbo Rapson ti o nse iwadi oro pe ki o fi iwe ipa pe won lati wa jeri.

Ninu awon obinrin oja ti nwon pe ni Alhaja Asabi Awe, on ni eniti o koko soro. O so wipe on ni Olori awon obinrin ti o nta aso ni oja Ereko, ni Opopo Victoria, ni ita Balogun ati niti Doherty. On je okan ninu awon ti o gba owo iso lowo awon obinrin ti o nta aso, o si so idi re ti nwon se sebe.

Ni asiko kan nigbati awon olopa bere si yo won lenu nidi oja won ti nwon ko jeki awon pate, ni on ba ko awon obinrin alaso yoku sodi ti awon lo ka Akinbiyi mo ile ise re wipe bi nwon ko ba fe ki awon pate ki nwon ko iso fun won ti awon yio ma pete nibe. Ogbeni Akinbiyi si so fun won pe, bi o ba je wipe lotito ni nwon nfe iso ki nwon mu owo ilele wa, nigbana ni ijoba yio gbagbo pe nitoto ni nwon nfe iso. Nigbati Town Council ba ri owo ilele won, yio gbagbo wipe nitoto ni awon enia na nfe iso.

Nitorina ki gbogbo awon Obinrin ti o ba fe iso na, ki enikokan mu Poun mefa owo ilele wa, eyi yio je asantele fun owo odun kan nigbati nwon ba ko iso na pari tan. Ogbeni Akinbiyi so fun awon wipe owo ti yio pari iso titun na yio to oke kan pelu abo poun.

Lehin eyi ni awon obinrin kokan ti o nfe iso bere si da owo poun mefa-mefa wa sodo on. Lehin ti a gba owo na jo tan, ni aba ko lo fun Town Clerk, ko fun wa ni iwe eri, sugbon o seleri lati fi risiti ranse si wa.

Oyinbo na bere pe, bi enia ba fe di okan ninu egbe awon obinrin na bawo ni yio ti se? Asabi Awe dahun pe, bi oluware ba ti san iye nkan ti egbe ba bu fun, o tan, awa ko si nse ilu, ati pelu bi iyawo Ogbeni Rapson ba fe, a le gba sinu egbe. Bi oro iwadi na ba ti nlo si ao ma fun yin ni irohin re

Obinrin kan ti o pe oruko re ni Abioye Dosunmu ni on ngbe No. 7 Ibomo Street l'Eko, o so wipe eran ni on ti nta ni Ebute-Metta sugbon fun igba kan on tun nta Awo ati Panu fun igba die. Nigbati on gbo wipe awon kan nkowe fun iso, on na ko. Oluwadi bere lowo re pe tani ba ko iwe na, o dahun pe eniti o ba on kowe na ngbe Ereko, sugbon o ti ku lehin ti o ba on kowe tan.

Oluwadi bere bi enikeni ba gba owo lowo re tabi ti o ba sanwo fun enikeni, Obinrin na so wipe agbedo o, on ko san epinni fun enikankan o.

## NWON GB'OYE AKAN'SE LOWO BASSEY



AMERIKA. Ere ese jija ti o bere larin Hogan (Kid) Bassey ati Davey Moore ara ile Amerika ni ilu Los Angeles, ija na gbe fun Davey Moore.

Ni akoko bere ija na, awon mejeji nle ponron enikini ko le mu enikeji sugbon nigbati ere na nlo bi igba ketala, a gbo wipe Davey Moore so ese si oju Bassey eje seyo nigbati eje na po ni nwon ba da ija na duro.

## Rogbodiyan Be Sile Ni Nyasaland

A gbo irohin wipe ni Salisbury ilu kan ni Nyasaland, nigbati awon enia pejo si eti igbo kan, awon pase fun awon enia na pe, ki nwon tuka kuro nibiti nwon gbe duro si nwon si nlo tiko-tiko lati se be, nigbana ni egbe omo ogun ti o ndabo bo ijoba ilu na yiabon si arin awon enia na enikan ninu awon enia na ku patapata awon enia meji si fara gbogbe.

Bi oro na ti je niyi. Awon egbe kan ti o nje (Nyasaland African National Congress) ti o ndite si ijoba lo ko wo inu igbo lo ti awon ogun Ijoba ilu na ati awon olu-[illegible] nwon sapamo si awon egbe ibile ti o nje Congress yi nse jamba fun awon oyinbo pupo. Sugbon awon ti o parojo nwonyi nse idilono jojo, o di enia mokandilogorin ti awon olopa dadu-ro fun ibimbiran, e n i a meta lo si ku patapata.

NOTICE

LAGOS RACE CLUB

The Lagos Race Club anuounces for the information of the general public that the admission or Gate Fee on Racing Days has been reduced to 5/- with effect from the forthcoming Easter Meeting.

OLADIPO MOORE
CHAIRMAN

# LAGOS TOWN COUNCIL

## Contract for Sewage Disposal

TENDERS are hereby invited for the clearance of Nightsoil in each of the following zones of Lagos:-

ZONE 1. Western Portion of Lagos Island, comprising Municipal Wards 'A' East, 'A' West 'B' East and 'B' West.

ZONE 2. The Eastern Portion of Lagos Island comprising Municipal Wards 'C' East C West, 'H' South: and Ikoyi and the Victoria Beach Area of Municipal Ward 'G'

ZONE 3. Lagos Mainland and Iddo Island comprising Municipal Wards 'D' 'E' East, 'E' West 'F' North and 'F' South.

CONDITIONS OF CONTRACT.

Tenders must provide for the clearance of Nightsoil in accordance with the following conditions:-

1 (a) In Zones 1 and 2, all sanitary pails in these Zones (including those in public latrines) totalling approximately 5,000 pails in each case, must be cleared.
(b) In Zones 3 all sanitary pails (including those in public latrines) which are at present serviced by the Council, totalling approximately 1,250 pails, must be cleared.

2 All sanitary pails must be emptied and cleared daily and the nightsoil therefrom must be removed by the Contractors to the Council's depots or to a specified tipping point on the foreshore.

3 The transportation of nightsoil from the Council's depots to the foreshore will be the responsibility of the Council, but the contractors will be required to tip nightsoil at the foreshore were no depots are provided.

4 Clearance of all pails must be carried out daily and the contract will provide for a penalty of five shillings per day which will be strictly enforced in respect of every pail not cleared.

5 Contractors must provide a labour force consisting of at least one labour for every 40 pails to be cleared and a literate headman to be in charge of a maximum of 360 pails. The headmen will be required to inspect personally every day all premises from which pails are cleared.

6 Contractors must provide drums for the collection of the nightsoil.

PROVISION OF BOND

Contractors will be required to enter into a bond with the Council for payment, in the event of default, of an amount equal to ten per cent of the value of the contract for a period of six months, and persons tendering must submit with their tenders the names of two substantial bondsmen who are willing to become bound with them for the due performance of the work.

METHOD OF TENDERING.

1. Personal tendering must quote the amount to be charged per pail per month for the clearance of nightsoil in accordance with the conditions set out above.

2. Seperate tenders must be submitted for each of the three zones.

3. ALL TENDERS must be enclosed in sealed envelopes endorsed outside "TENDER FOR SEWAGE DISPOSAL" and must be addressed to the Town Clerk, so as to reach him not later than 2 p.m. on Tuesday, 24th March 1959.

4. The Council is not bound to accept the lowest or any tender.

D. M. O. AKINBIYI
Town Clerk.

MUNICIPAL BUILDINGS,
LAGOS, 14th MARCH, 1959.




## Lagos Executive Development Board

### PUBLIC WARNING

#### PLANNING CONTROL

It has come to the Board's notice that in spite of regular public warning by the Board, Land is being sold and purchased for building purposes in Lagos Township, (especially in certain parts of Suru-Lere and East of Yaba) without previous consultation with the Board's Town Planning Department for information as to how the land or plan for building on them are affected by town planning proposals.

The Board has been further concerned to find that buildings which do not comply with the building Bye-Laws or conform with plans approved by the Board are, in fact, erected on such Lands.

Before proceeding to divide any land within the Township in to lots for the purpose of sale or building upon, an owner must, by law first submit two indentical plans of the land to the Board for aproval.

These plans must show the proposed division of the land into lots and whatever provision if any, has been made for roads.

The public should be aware that unauthorised building within Lagos Township is liable to heavy penalties, including total demolition of the unauthorised building, together with fines and/or imprisonment. It is therefore in the interest of intending purchasers of land for building purpose as well as owners of property wishing to alter buildings or rebuild in Lagos Township, that before purchasing land or buildings and before preparing any building plans, they should first consult the Town Planning Department of the Board for necessary guidance.

Inquiries should be made in writing to the Chief Executive Officer or by visit to the Town Planning Department, Lagos Excutive Development Board, Reclamation Road, Lagos between the hours of 8 a.m. and 10 a.m. Monday to Friday and 8 a.m. to 9 a.m. on Saturday.

R. A. J. CORK
Ag. Chief Executive Officer

# NISISIYI !

## FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWỌN ONIṢOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

**Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai**

**muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.**

ẸNYIN KỌLẸKỌLẸ ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao ṣe fun yin lọfẹ.


## Aseku Pani L'obinrin

O bẹrẹ ninu iwe wa ọsẹ to kọja

Ti Ọkọ ba lọ si oko Iyawo a wa nile bi Iyawo ba lo Ọja Agiri a ma ṣọle bayi ni nwon nse titi di igbati Ọjọ ije yi kụ ọjọ mẹsan, ti Agiri si lọ si oko lati lọ se Ipalẹmọ. Bi Agiri ti nlọ si oko o ya sile Ọba lati ki pe o dabọ. Ọba si tun ran leti adehun won. Ọjọ kẹta ti Agiri kuro nile ni Ọba ranṣẹ pe Iyawo re, o si bẹ titi ki o fi ibiti bale rẹ fi oruka ijẹlo si han on

Obinrin Ọdalẹ yi si mu Ọba lọ sile larin oru o si fi orukọ na fun Ọba. Ọba si ba a pinnu pe bi okọ, rẹ ba le ti ipa ọrọ yi ku, on yio mu Abatenijẹ Iyawo re se aya. eyi nipe Abatenijẹ yio di Ayaba lẹhin iku Ọkọ rẹ. Nwon si ti gbagbe wipe eniti Ọlọrun ko pa Ọba ko le pa a Ni ọjọ keji ti Ọba gba Oruka yi ni o lo ju sinu odo nla kan ti o san gba ilu kọja. Omi yi ṣan titi o fi gba idi oko Agiri koja pẹlu ni nkan bi ibusọ mejila sile.

Bi Ọba ti ju Oruka yi sinu Odo yi ẹnu ẹja nla kan lo bọ si. Ẹja yi si luwẹ titi o fi de idi oko Agiri. Fun gbogbo akoko yi ni Abatẹnijẹ fi npale ẹru rẹ mọ sile Ọba Ni ireti pe laisi aniani Agiri yio di ologbe ati pe on yio si di ayo Ayaba

ka ma fa ọrọ gun lọ titi Nigbati ọjọ ije yi ku ọjọ mẹta Agiri mura lati wa sile. Bi o ti sare lọwẹ ni eti odo ni ori ẹja nla kan ti o so soke lati inu ibu wa o si pa a. Bi o ti de aba lati la ọfun ẹja yi Oruka na lo ba ni bẹ pẹlu nyọ ati ironu ni o fi elu wa silẹ. gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ, Nigbati o dele ko ri oju Iyawo nilẹ mọ, ipade wọn wa dabi ti ologbo ati ekuele Nigbati o di ọjọ keji o pe Iyawo lati lọ wo oruka ijẹlo. Iyawo ko tilẹ wo loju. On papa si lọ wo bẹ ko ri mọ. Nigbati o di ọjọ kẹta tiṣe ojo ije, Ọba ti ranṣẹ pe Agiri. gbogbo ilu si ti pejo si Afin lati wa wo iku ẹlẹya. "Gbogbo aiye nreti ẹlẹya nibo lẹ fi ti Oluwa si".

Ki Agiri to de Afin Ọba, Abatẹnijẹ ti wẹ o ti mura gẹgẹbi ti Arede, o ti joko ti Ọba lati fi oju ri ẹsin Ọko rẹ. O dabi owe ti o wipe "Ada siti lorun Iyawo odogo Ẹlẹlila nwa ẹlila o ni ki nwon jẹ ki oko on de, beni Ọko re ko gbẹ elila".

Bayi Ọba dide duro ti o si bẹrẹ si soro bayi pe. Ẹnyin ara ilu mi gbogbo, ẹ ku ijoko, nkan ti a fi pejo si loni ni lati mo nkan ti y'o gbehin osika boya rere ni tabi buburu gẹgẹbi a a Agiri Asaṣa, beni Ọgbọn Ọlọgbọn ki jẹki a pe agba ni were.

Bayi ni Ọba juko ti o si pe sarin Igbimo pe ki o mu oruka Ijẹlo wa, Agiri rin soke-sodo, o yan larin won, beni gbogbo won bẹrẹ si fi se ẹlẹya wipe- O tan nidi rọ, mu oruka na silẹ ka rii, Ojo ika to su yi ako mo ori ẹniti yio ro le

Bayi ni Agiri mu Oruka jade fun Ọba, Ariwo gbera nilẹ si re Oke Orun. Ọro ya Ọba lẹnu, o si binu pe Abatenijẹ ni Ọdalẹ Obinrin o pe awon apanin, nwon si bẹ lori si waju Ọba. Ọba si mu ileri rẹ ṣẹ fun Agiri Bayi ni Agiri bi Olowo, Ọlọla ati Olokiki ti Iyawo rẹ si di ero isalu Ọrun. Ki Ọlorun ma gbe wa pade iru Obinrin bayi o.

**Lati ọwọ Arowolo Ọshọtuy-**

## ỌJỌ ISINMI FUN ỌDUN IMALE

ẸKO. Gomina agba ti fi aṣẹ si wipe iwonyi ni awon ojo iṣinmi fun ọdun awon Imale jake-jado ile Nigeria. Friday 10th ati Saturday 11th oṣu April 1959 ki o jẹ ọjọ isinmi fun ọdun kekere (Id-el-Fitri).

Wednesday 17th ati Thursday 18th osu June 1959, ki o je ojo isinmi fun odun nla (Id-el-Kabir) Tuesday 15th osn September 1959, ki o je ojo isnmi fun ojo ibi Anabi Mohamad (Maoludun Nabiu).

## ẸLẸRI SA'E YI KOTU KA NIGBA MEJE

IBADAN Ọkunrin kan ti a npe ni Lasisi Abidoye ni awọn ọlọpa mu wa jeri nipa gẹgẹbi owo kan ti ṣe s nu lọdọ awọn Olowo ori nilu Lalupọn.

Ọgbẹni Begho ti o nṣe adajọ ninu kotu na ri oye wipe ẹlẹri na ko fẹ fi ododo ọrọ na han gẹgẹbi o ti ri, nitorina kio sare yi kotu ka nigba meje. lẹhin na ko tun bẹrẹ eri jijẹ rẹ.

Nigbati igbedun ẹlẹri na. o sọ gan, gẹgẹbi ọrọ Alli Idowu akọwe olowo Ori ni ilu Lalupọn na ti ri. Nigba na ni adajọ da silẹ pe ki o ma lọ ni alafia.

# ELETI - OFE

A-NIU-WON KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 6??. SATURDAY MAR. 21 - MAR. 27, 1959.


# Ominira Wa Ku Si Dede.

Ida akoso ara-ẹni ṣe ti ijọba Oke-ọya gba lọjọ ọsẹ tokoja yi jẹ orire fun gbogbo-gbo enia ilẹ Nigeria nitoripe, lati nkan bi ọdun meji s'ẹhin ti awọn ijọba agbegbe Ila-Orun ati ijọba Iwọ-Orun ti gba aṣe adaṣe akoso iṣẹ ijọba wọn fun arawọn ni gbogbo enia ti nf'oju s'ọna fun ti ijọba Ariwa ti ọlọla Sir Ahmadu Bello, ti iṣe oloye Sardauna Ṣokoto jẹ Olotu ijọba na wipe ki o gba aṣẹ iṣe akoso ijọba ilẹ Hausa fun'rawọn ki imọ ati iṣe wa le papọ mọrawọn fun ati gba Ominira ni agbatan fun gbogbo ilẹ Nigeria.

Nisisiyi, a ni ifọkanbale wipe laisi ani-ani, ko si ohun ti awọn alaṣẹ le fi ṣe bojuboju fun wa mọ ju wipe ki nwọn ṣe iyọnda fun wa, gẹgẹbi ifokasi ati ileri ti nwọn ti ṣe fun wa wipe ni ọjọ kini oṣu October, 1960, ni ọjọ idande wa ni ilẹ Nigeria ti awa na yio di ọkan ninu awọn Orilẹ-ede ti o ti ko ẹkọ ti o si ti bọ ajaga awọn akọni l'ẹkọ kuro lọrun ti ao duro fun arawa.

Nitorina, a ba awọn Alakoso ijọba Oke Ọya yọ, a si fi ọpẹ fun awọn akonijẹ ẹgbẹ Afẹnfẹre (Action Group) fun wahala ati lakaye won ti nwọn fi ṣe eto ti o mu wa de aye ti a wa loni yi jakejado ilẹ Nigeria.


# Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA, o dara pupọ fun awọn ọmọde.

"Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma nba ọmọ ja ni asiko chin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo ẹgbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Mẹji Ab̀ọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


# Obo Olowo Fi Oye Da Awolowo Lola



Oba Ọlọwọ se ajodun kejidilogun ti o gori oye rẹ gẹgẹbi Oba Ọlagbegi Keji, tilu Ọwọ. Ninu ayọ ti ajọdun na, Oba Ọlagbegi fi oye da awọn ijinni enia meji nwọnyi lọla.

Ẹnikini ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o fi joye Odofin ilu Ọwọ, ẹnikeji ni Oloye Akin Dekọ ti o fi joye Salague ilu Ọwọ.

A gbọ wipe nigbati nwọn ma fi Awolowo joye yi, ko si nibẹ, nwọn mu oye na lọ ba nile ni. Ẹniketa ti nwọn tun fi joye ni Alufa Ẹni-ọwọ D. A. Fawẹhinmi, ti nwọn fi joye Ọrunbato ilu Ọwọ.

# Meta Ni Ibadan

Awọn opitan so pe, Ibadan ti o mbẹ yi ni eketa Ibadan. akoko, ogun lo fo o Ibadan keji ija gboro ti ọku ti-o ya mo egungun lori lo fo o. Eketa rẹ ni o' mbẹ loni yi.

# Itan Ogunbebe

Ogunbebe ri Ogulutu, o wo o ni awomoju, gbogbo awon ti o wa nibe si se ha! Nwon bere lowo Ogulutu pe kini ohun ti o da awon mejeji po? O dahun pe amoni loju ko ba ni wi, agbon isale lo nwo.




## Eniti Oloyun Loju Aia Bimo

AKURE. Omobinrin omo ile eko kan ni oloyun lojiji la'je wipe o ti ni oko soju ona awon obi re pe wipe tani fun ni oyun? o dahun pe rara! on ko loyun, bikose wipe on nsanra ni. Awon obi re fi sile. Nigbati o to bi iwon osu meji si, awon obi re tun pe, won bere pe tani fun e loyun se?

Omobinrin na dahun wipe emi koiti loko bawo ni ena se le ni oyun lai loko? Iya re pe si koro o bere lowo re tani nun ori re Omo na dahun pe, enikan ko gun ori mi, sugbon nigbakugba ti mo ba sun ni mo nsaba lala ri oluko kan ti o nje Akerele ti o si nwa ki mi mole.

Iya re bere pe iwo pelu re na ti mo ara nyin ri? o dahun pe rara O tun bere pe iwo ha le sapejuwe ohun kan lara okunrin na o dahun pe beni apa obe kan wa niwaju re ami dudu nla kan wa nigba aiya re. N na ilewe Opopo Labiran lo ti nse oluko.

Gegebi iro ti awon obi omo na gbo iya omobinrin na dakan lo si Ibadan, o lo si ilewe Opopo Labiran O ri Oluko na ti o nje Akerele gbogbo ami ti omobinrin na sa apejuwe lo wa lara oluko na. Iya omo na pe e o bere pe ese ti o fi fun omo on ni oyun ti o dake ti ko so ohun kan.

Oluko Akerele fi owo mu ori, o wipe nibo ni omo wa Iya dahun pe ni Akure lo ngbe. Oluko so pe lati ojo ti on ti daiye, on ko kuro ni ilu Ibadan ri Asehinwa asehinbo nwon ni ki nwon jeki aboyun na bimo na ki a mo eniti omo jo. Nigbati nwon bimo na o si jo oluko na de gongo Oluko na ko fe gba omo yi ayafi nigbati ejo na de kotu ni adajo so pe ki oluko lo gba omo na ki obinrin si di iyawo re.

# Itan Elegbeje Ado

(O bẹrẹ ninu Iwe wa Ọsẹ to kọja)

Bi won ti fẹ ma sare lọ sọdọ Olori wọn, bẹni Elegbeje-ado ba fi ẹnu bọ ọfọ pe, fọn fọn ti fọn asun ma parada ni ti igi aja, ẹsun lesẹkan na gbogbo wọn si sun lọ bamubamu. Nigbati gbogbo wọn wa sun lọ dada jagun labi wa lọ si ọdọ o wa o si dumbu gbogbo wọn ni ọkan kan tan, o tun wa lọ duro si ibi aye rẹ.

"IṢẸ WA KAN ẸBỌRA ỌṢUDUN GIDI GAN WA YI"

Nigbati o wa reti wọn titi ti kori wọn ohun to wa ṣe nipe o wa ran oji (afẹfẹ nla) siwọn pe kio ko gbogbo awọn ẹda enia to ba wa ni itosi ile on. Bi Elegbeje ado ti nro gẹgẹbi on yio ti ṣe ṣẹgun rẹ, bẹni atẹgun nla yi de. o si da jagun yi lamu pupọju, to jẹ wipe o fẹrẹ bọ ohun yọ pe kini on wa wa si ihin atẹgun yi si gbe sanlẹ to jẹ pe o to iṣẹju mẹdogun kio to le dide nile dide tio dide. ọwọ lo fi bọ apo rẹ, tio si yọ ado kan jade lapo ni o ba bẹrẹ si ni fi l[illegible]akiri, to bẹ gẹ ti atẹgun na fi wa duro diduro ti o duro o wa to bi iṣẹju marun o wa ni iṣẹ to wa ṣe nisisiyi o gbera ni ile o fi ẹsẹ le ọna ile Ẹbọra Ọṣudun, Ọṣudun kẹ niyi, ko mọ pe atẹgun yẹn ko ti pa ẹda enia to nyọ on lẹnu ọkan rẹ si ti balẹ gẹgẹbi ti Tolotolo. On min. fin fin fin koma pe ẹda enia. ju Ẹbọra lọ lọna-kọna.

ELEGBEJE ADO DE ẸNU ỌNA RẸ

Dide ti jagun de enu ọna ọhun tio kọkọ ṣe nipe, oju ibọn kan silẹ to jẹpe ibọn na ro gẹgẹbi agba ti wọn nrọ ni Apapa. Gbigbọ tio gbọ didun ibọn yi ibẹru bojo ti mu, on sa sihin, sa sọhun riri ti jagun ri, ohun tio ṣe nipe o bu si ẹrin kekeke, oni ọwọ tẹ ọ wayi, ẹrin ti Ẹbọra pi gbọ owo ibi ti o ti gbọ ẹrin mu, osiri jagun ti o duro bi Ogun ode

Ohun tio koko wi nipe. Ẹbora niẹ tabi ẹda enia ? jagun dahun pe, ẹda enia tio ju Ẹbora lo ni Ẹbora :- kini o wa de ihin, opan pao loni gbogbo awon eda enia egbe rẹ ki nde ibugbe mi ki o pada si ibugbe re ti o ti wa. Elegbeje-ado:- kini o wi yi ? afira mija ejo tio ba yi ehin re pada nisinyi, iya yio si jeo ni isẹju akon yi' toripe emi yio fi ye o pe on ti nko ile o ti ko gbegi temi yio si ya e lenu, riri ti o ri miyi moju baba nla re lo.

(koiti pari)

# Itan Ajapa Ati Ekun

APA XVI

Lati ọwọ Ẹṣọ

Ikoriko ti Ajapa gbojule pe on ni yio gba on kuro lọwọ awọn Igba ti o nle e, nigbati Koriko gboju soke ti o ri nkan ra ti o ntu oruku bọ wa, ko kuku ri nkan na gan ti o nturuku, ati pẹlu wipe Koriko ko ri iru rẹ ri nje ki baba yi (Ajapa) ma ba ko tirẹ wa ba ti on, aiya Koriko ja, o nṣu, o ntọ, lo ba salọ, ni Ajapa ba tun bẹrẹ ere sisa, o ni hun! awọn eleyi lagbara lasan, ṣugbọn nwọn ko to gbẹkẹle.

Bi o ti tun nsare lọ, bẹni o pade Ẹfọn. Ajapa sare kọja rẹ, Ẹfọn kesi, o ni Ajapa ! kilode ti iwọ agbalagba nsare jiajia bayi?.

Ajapa dahun pe titobi ko nṣe agbara, ohun ti o nle emi agbalagba ti mo sare, ti mo si nlagun bayi bi Ẹfọn ba ri oruku rẹ lasan ko ni duro wo ẹhin mọ.

Ori Ẹfọn gbona si abuku ti Ajapa fi kan a, o ni ki Ajapa duro lẹhin on ki on pẹlu nkan na jijọ koju. Ẹfọn mi iwo ori rẹ wo, o fọn ikun imu rẹ wo, o fo sọtun, o fo si osi nibiti o gbe ndanrawo, ni awọn Igba turuku yọ ni okere, Ajapa kigbe pe nwọn mbọ !

Ẹfọn gbojusoke, o ri eruku ti o nku bọ lọdọ rẹ ṣugbọn oju rẹ ko to ohun na ti o nturuku ẹfon ni, hepiripa! emi ko male duro ba ohun ti nko ri ja. Nigbati eruku na kusata Ẹfon ko ri nkan ti o nturuku eru ba a lo ba fi ori le inu papa.

Ajapa ni hun, ṣio, igi ti a fẹhinti ,ti ko gbani duro bi o ba wo luni, o ba le pani bi? ni Ajapa na ba tun gbesi. Bi o ti tun nsare lo, ọmọ Ẹkun ti o ti lugọ lati owuro wa ti o nreti ẹran ti yio pa je, ri Ajapa bi o ti nsare lọ o sare tele, o nse baba baba Ajapa gbọ o duro Ẹkun bere, pe kini ohun ti o nle nyin bayi Ajapa ko ejọ, o rohin pe awọn Igba lo nle on.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ, ẹ gbo bi Ẹkun ti leri lẹka, ti o jẹ pe. o si tun salọ ni.

Koiti pari.

**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE**

L'ỌSỌSẸ O KUN FUN IROHIN ALADUN

# Ijoba Oke-Oya Di Alakoso Arawon



Lọjọ Sunday 15th oṣu March, 1959, ni awon Hausa di alakoso ara won, eyiti awọn agbegbe Ila-Orun ati Iwọ-Orun ti bẹrẹ lati inu oṣu September, 1957. Ni ọrọ kan gbogbo ilẹ Nigeria lo nṣe akoso ara wọn. Ohun o ku ti gbogbo ile Nigeria nreti nisisiyi ni ọjọ Idande wa, ọjọ 1st Oṣu Oct. 1960, nigbati gbogbo Apapọ ilẹ Nigeria wa yio gba Ominira.

Ninu osu May ti o mbo yi ni Ijoye kan ti nwon npe ni Duke of Gloucester yio gunlẹ si ilu Zaria, yio ti ibe lo si igboro Kano lẹhin na yio wa si Kaduna, nibiti iwon ẹdẹgbaji ẹṣin gbe nduro de lati ṣe ere Durbar fun.

A fi eyi ki ijoba Oke-Ọya ku orire, pataki Sir Ahmadu Bello, Sardauna Shokoto eniti o je asiwaju akonije Ijoba na.

# EBUN ILERA



Ara-lile, agbara ati okun-inu ni isura ti o koja idiyele, awon ebun ẹda ti o dara julọ ni. Ko si onjẹ miran ti o nfun ni l'okun-ilera atata bi Ovaltine, ohun ti a fi peelo rẹ ni onjẹ atẹjẹse ati eyi ti o nfun ara ni okun. Mimu Ovaltine lojojumọ ni ona ti o dara julọ ti o si rorun julọ lati fun ni ni opọlọpọ ilera ti o dara tẹlẹ, lati ri i daju pe a ni okun lojojumọ ati idera, orun asunwora. Egbẹgbẹrun awọn ọlọmọde ni nwọn mọ anfani atata ti Ovaltine ni, onjẹ olomi ti o dara julọ ni.





# Fija F'olorun Ja

Ọkunrin kan dide o lọ ji adiẹ kan gbe Faru o si pa a jẹ. Nigbati lie mọ ti aladiẹ ko ri adiẹ rẹ, o ni enit'o ji adiẹ on gbe mo fi fun Ọlọrun. O si dakẹ.

Lẹsẹkanna ihihu de bẹrẹ ri hu lara ọkunrin ole yi iyẹ adiẹ bo o lara patapata eru wa bẹrẹ si ba a. ko le jado mọ rara, inu iyara lo ku ti o ngbe o damu patapata ko mọ ohun ti on ti on o se mo.

Ninu iyara to wa, ebi bẹrẹ si pa a bẹni ode ko se fun u rara nigbati o ... o titi, ti ko mọ ohun ti on o se mọ, opinnu lati ku. Ṣugbọn o sọ pe bi o ba lọ ni ile, a mọ ohun to ale ni lọ o ni on kuku ti mọ pe ohun to ma pa on li on ra owọ le yi on kuku lọ ji adiẹ rẹ yoku gbe bi on ba ku wayi, o tẹ on lọrun. Nigbati o di alẹ, o lọ gbe agbebọ adiẹ n'a kanṣoṣo ti o ku lọwọ aladiẹ ns o paa jẹ

Nigbati ilẹ mọ ti aladiẹ ko ri adiẹ rẹ kan yoku mọ o ta a lara, o dun u, o fi ibinu tẹnubọ epe ni s'sẹ pe Ṣango lo ma pa en'to gbe on ladiẹ lọ Ọya lo ma pa a, inu eru lo ma ku si Ṣọpọnna ni yio fi igi imu rẹ fun fere ati ọpọlọpọ epe buruku buruku bẹ lo nṣẹ.

Bi o ti nṣepe yen enito ji adiẹ rẹ pa jẹ, wa ninu ile, ko le ja de, ṣugbọn o ngbọ epe ti o nṣe sọ ọ o si nreti iku nigbakugba. Ṣugbọn o ya a lẹnu pupọ lati ri i pe bi aladiẹ ti nṣe pe sọ ole bẹni iyẹ ati ihuhu ara rẹ nre bọ silẹ nikọkan titi gbogbo rẹ fi re tan ti ara rẹ si dan sipo rẹ pada. Fi eyi ko ogbon lakoko igbati ọran ba se ọ ki o fi ọran rẹ le Ọlọrun Ọba lọwọ. Ki o si mọ daju pe Ọlọrun yio gbẹja rẹ

Ṣugbọn bi o ba gbegbe Ọlọrun ti o ba gbẹkẹle agbara ati ogbon ori ara rẹ bẹni Ọlọrun yio gbagbe rẹ ti yio si fi o silẹ fun agbara ati ogbon ori ara rẹ. O si daju pe "Aiẹtunjẹ iya" li o ma jẹ nigbana "Fi ija f'Ọlorun ra fowo lẹran" toto o ṣe bi owe o-

Abiola Bolarinwa

# LAGOS RACE CLUB

## EASTER MEETING 1959.

### Saturday 28th, Monday 30th, March, Saturdays 4th, 11th & 18th April 1959.

**FIRST DAY**

| | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Seven Furlongs Handicap-Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Five furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | THE JUBILEE CUP Nine Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

**SECOND DAY**

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4- 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO 6 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO 7 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5. 45 p.m. |
| RACE No 8 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6. 15 p.m. |

**THIRD DAY**

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE No 8 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

**FOURTH DAY**

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO 1 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO 4 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | THE OPEN RACE TEN FURLONGS | 6. 15 p.m |

**FIFTH DAY**

| | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE NO 3 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO 4 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | THE OMOLOLU CHALLENGE CUP SIX FURLONGS HANDICAP TOP DIVISION | 6.15 p.m. |

No. 53

# INLAND WATERWAYS DEPT.

## Notice No. 16 Of 1959

### LAGOS/APAPA FERRY

It is notified for general information that the following Lagos/Apapa Ferry Time Table will be observed over the Easter Holiday period.

GOOD FRIDAY 27th MARCH.
Normal Sunday Ferry services EXCEPT that the last Ferry will leave Apapa at 8.00 p.m.

SATURDAY 28th MARCH.
Normal Saturday Service.

EASTER SUNDAY 29th MARCH.
Normal Sunday Service.

EASTER MONDAY 30th MARCH.
Normal Sunday Service.

**C. ATKINSON, Director,**
**Inland Waterways Department**





## OGUN ARAN EJO INU

Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn arun buruku ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran bẹni o npa enyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6
Owo ọkọ si jẹ 1/.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street.
P. O. x 2, Ebute Meta


Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street Lagos. P.O. Box 467 Phone 23370